BON SECOURS HEALTH SYSTEM

**Eto /Ilana**

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| Title: | Iranlọwọ owo fun Alaisan | | Deeti: | 04/01//2016 |
| | | | Ọjọ ti a parọ Ẹda ti tẹlẹ: | 01/12/2015 |
| Ìsọ̀rí: | SYS.MIS.FAP | Ojú Ewé 1 of 15 | Ẹni ti o fọwọ sii: | Ajọ BSHSI |

## ETO

O jẹ eto ile iṣe Bon Secours Health System, Inc.("BSHSI") lati jẹ ki eto ilera wa fun gbogbo eniyan to nilo rẹ. BSHSI nṣe itọju gbogbo awọn alaisan boya wọn ni eto adojutofo tabi wọn ko ni, tiyi tiyi, tọwọtọwọ , pẹlu oju aanu, ni gbogbo igba ti wọn ba wa si ile iwosan wa, ṣiṣe itọju, pipari itọju, ati eto ìdíyelé, ati eto owo gbigba. A gbe eto yi kalẹ pẹlu ibamu pẹlu Abala 501(r) ti Òfin Eto Owo Gbigba Abẹ́lé ti ọdun 1986 (Section 501(r) of the Internal Revenue Code of 1986), gẹgẹ bi a ti ṣe atunṣe rẹ , ti o niiṣe pẹlu owo iranwọ ati awọn eto itọju pajawiri, gbendeke to wa fun awon eniyan to lẹtọ si eto iranwọ owó, ati idiyele ti ko ju ara lọ ati awọn igbesẹ owo gbigba, ti a ni lati ṣe itumọ rẹ bi o ti yẹ.

## IBI TÍ Ó SISẸ́ DÉ

Eto yii wa fun gbogbo ẹka itọju awọn aisan to le ni ile iṣe BSHSI (BSHSI acute care ) ati awọn iyara itọju pajawiri.

## AWỌN ITUMỌ

Iye Owo Ti O Wa Fun Sisan Fun Eyikeyi Itọju (Amounts Generally Billed ,AGB) – Iye owo ti o wa fun sisan fun eyikeyi itọju tumọ si iye idiyele to wa fun awọn alaisan fun itọju pajawiri ati awọn itọju miran ti wọn ni eto adojutofo. Idiyele fun awọn alaisan ti wọn lẹtọ si iranwọ owo ko ni ju Iye owo ti o wa fun sisan fun eyikeyi itọju ("AGB") lọ fun awọn itọju bẹẹ. Awọn idiyele yii da lori owo ti ajọ Medicare ati awọn alaisan to nsan owo funra wọn saba maa nsan fun itọju pajawiri ati awọn itọju miran. A o gba owo ti ile iṣẹ Adojutofo yoo san ati owo ti alaisan yoo san funrarẹ, to ba jẹ pe yoo san owo, O lee mọ AGB nipa lilo ọna ẹyin wiwo ti a mọ si "looking back method per 26 CFR §1.501(r)". Wo Afikun A fun alaye kikun nipa ẹ̀dínwó AGB

Gbese Tí Kò Ṣe É San Mọ́ – Iye owo to wa ninu akanti gbese alaisan kan tabi oniduro ti a ti fagile pe koṣee gba pada mọ
Iṣẹ Abẹ Fun Ṣise-Ara-loge eyi ti o wa fun lati maa ṣe ara loge.

Ile Iwosan To Nṣe Itọju Ọpọlọpọ  Awọn  Alaisan Ti Ko Lowo Lọwọ ( DSH) –  Ile iwosan to nṣe itọju awọn alaisan ti wọn ngba owo osu kekere ti wọn si ngba owo lọwọ awọn ajọ Medicaid and ati eto Medicare lati fi ṣe owo itọju awọn alaisan ti won ko ni eto adojutofo.

Awọn Itọju To Yẹ Fun Eto Iranwọ – Awọn wọnyi wa ninu itọju ti BSHSI npese ni gbogbo ile iwosan wọn ti wọn lẹtọ si iranwọ owo:

(A) Itọju pajawiri ti a seto ninu iyara itọju pajawiri.
(B) Awọn eto iwosan lojiji fun awọn aisan to lee mu ẹmi lọ ti a nṣe ninu iyara ile iwosan ti ko si fun iwosan pajawiri
(C) Awọn itọju to nilo eto iwosan.

Aisan To Nilo Itọju Pajawiri  –  Aisan to n fi ara rẹ han pẹlu awọn ami to le koko ( pẹlu ara riro gooro), ti o jẹ pe ẹni ti kii ṣe oníṣègùn, to jẹ pe eni to ni imọ diẹ nipa eto ilera  ati oogun yoo lee sọ pe aisi itọju lasiko yoo yọri si:

(A) Ọpọlọpọ ewu fun ilera ẹni naa tabi to ba jẹ aboyun, ilera obinrin naa tabi ti ọmọ rẹ;
(B) Siṣe idiwọ gidigidi fun sịṣẹ iṣẹ́ agọ ara; tabi
(C) Aile ṣiṣẹ awọn eya ara.

Owo To Nwọle Fun Idile –  Gbogbo owo tabi awọn nkan ini ti a le yi pada si owo to nwọle fun enikan tabi ti a fun ẹnikan. Awọn nkan ti a ko ka kun owo ni: awọn anfani ti kii ṣe owo ati awọn iranwọ lati ọdọ ijọba, bii eto iranwọ fun onjẹ ati ibugbe, ati iranwọ fun eto ẹkọ.

Awọn Eto Ilana Ijoba Apapọ fun Àìní (Federal Poverty Guidelines) – Ijọba Ilẹ Amẹrika nlo gbedeke àìní ti ịjọba Apapọ ( The Federal Poverty Level) lati ṣe itumọ bi alaisan/ẹbi alaisan ṣe tòsì si lati lee lo eto yi.  O da lori owo to nwọle fun idile ni ọdun kan, sugbọn kii ṣe gbogbo ọrọ̀ won, iye owo awọn nkan ti wọn nra lọdun tabi ṣiṣe agbeyẹwo bi wọn nṣe njẹ igbadun si (AFIKUN B). Ile Iṣe ịjọba ịlẹ Amẹrika to wa fun eto Ilera ati Ọ̀rọ̀ Ọmọ Eniyan (U.S. Department of Health and Human Services) maa nṣe iyipada si awọn ilana àìní ( poverty guidelines)  lọdọdun ninu Àkọsílẹ̀ ịjoba Apapọ (Federal Register) nigbakugba ti atunṣe ba wa.

Owọ Ti Ko Ṣee Din – owo to wa fun sisan fun awọn itọju kan ti awọn alaisan nifẹsi nigba ti wọn ngba itọju.

Oniduro – Alaisan, Onitọju, tabi awọn ẹniyan tabi ile iṣẹ ti wọn ni lati san owo itọju eto ilera
Olori Idile–  Eniyan ti wọn kọ orukọ rẹ sinu iwe àkọsílẹ̀ owó ori  gẹgẹ bi “Olori Idile”

Alainilelori  -  Eniyan ti ko ni ibugbe to ngbe ni gbogbo igba, ti o le maa gbe ni awọn opopona; gbe ni ibudo awọn ti ko ni ile lori, awon ile ijọsin, ninu ile tabi ninu ọkọ ti wọn patì; tabi ninu eyikeyi ibugbe ti ko fi ẹsẹ mulẹ tabi to wa fun igba diẹ   A lee sọ pẹ eniyan ko nile lori to ba jẹ pe iru ẹni bẹe “darapọ mọ” oriṣiriṣi ọrẹ ati/tabi awọn eniyan mọlẹbi  fun ọjọ to ju aadọrun ọjọ lọ.

Awọn Eniyan Inu Idile (“Ti Ko Da Duro”) – Awọn eniyan ti won “ngbe” ninu idile ti Olori idile ti sọ nipa wọn ninu àkọsílẹ̀ iwe owo ori.

Ile Ise To Nṣe Ayẹwo Awọn To Lẹtọ Láti Gbà Iṣẹ́ Eto Ilera Ṣe(Medical Eligibility Vendor)/ Siṣe Alagbawi Fun Iranwọ Fun Eto Ilera (Medical Assistance Advocacy) – Ile iṣe to nṣe Alagbawi,  ti BSHIS gbe iṣe eto ayẹwo awọn alaisan fun awọn eto ijọba ati eto iranwọ owo ile iṣẹ BSHIS.

Awọn Itọju to Nilo Eto Iwosan (Medically Necessary Services) – Awọn eto ilera to wulo fun didena, ṣisayẹwo, tabi wiwo aisan, oju apa, ailera, arun, tabi ami aisan ti o si ba ilana iṣẹ iṣegun oyinbo mu. Ninu eyikeyi awọn ipo yi, ti iṣẹlẹ naa ba gbe ami aisan to buru jade tabi awọn ayipada buruku nipa oogun lilo, nigba naa , o ṣe pataki lati se eto ilera to nilo fun iwosan.

Awọn Eto Ti Ko Lẹtọ - Eyi ni awọn awọn eto ilera ti ko ni ẹtọ lati gba owo iranwọ labẹ eto yi:

(A) Awon itọju sise fun awọn to ni ijamba. Sisan owo yi wa ni ibamu pẹlu awọn ofin to ṣọ pe alàgàta ni lati san owo to jẹ, to ba tilẹ jẹ pe awọn igbeṣẹ ofin yii waye lẹyin igba ti wọn ti fi ontẹ lu eto lilẹtọ si Eto Iranwọ Owo Fun Alaisan (Patient Financial Assistance Program). Ti eto owo lati ọdọ alàgàta ba wa, BSHIS yoo gba eyi to ku ninu gbese naa lọwọ alàgàta, ti ko ba si eto owo lati ọdọ alàgàta, alaisan lee beere fun owo iranwọ .

(B) Awọn eto ilera ti ko pọn dandan bi eto iṣe ara loge ati awọn eto ti owo wọn ko yipada (flat rate procedures) ati awọn alaisan ti wọn ni eto adojutofo sugbọn ti wọn yan lati ma lo eto adojutofo wọn, awọn ohun elo ile iwosan ti kii tete bajẹ, gbigba itọju ninu ile ati sisọ ogun fun lilo.

Awọn Ilana Labẹ ọfin

Nipa ṣiṣe amulo eto yi, BSHIS yoo tẹle gbogbo ofin ijọba apapọ, ijọba ipinlẹ, ati ti ibilẹ, ati awọn ofin to niiṣe pẹlu awọn ịsẹ siṣe labẹ eto yi.

## ILANA

Idi fun ilana yi ni fun ile iṣẹ BSHSI lati ṣe ayẹwo lati mọ boya awọn eniyan ati ẹbi wọn to koju oṣuwọn fun eto adojutofo ti ijọba apapọ, ti ijọba ipinlẹ ati ti ijọba ibilẹ tabi eto Iranwọ Owo fun awọn Alaisan ti Bọn Secours (Bon Secours Patient Financial Assistance Program, "FAP"). Kikopa ninu eto yii fun ẹnikẹni, da lori kikọ iwe ibeere fun iranwọ owo pẹlu gbogbo iwe to yẹ. Alaisan to ba kọ lati kọ iwe ibeere fun iranwọ bo ti tọ ti ko si fi awọn iwe to yẹ silẹ ko ni lẹtọ lati gba owo iranwọ labẹ eto yii. (iyẹn, to ba jẹ pe alaisan naa ti gba italolobo gẹgẹ bi o ti wa ninu ilana ofin Abala 501(r). Wo AFIKUN C fun alaye nipa bi awọn alaisan ṣe lee gba iwe ibeere fun owo iranwọ.

BSHSI ni ireti pe gbogbo awọn alaisan yoo ṣe ayẹwo fun awọn eto adojutofo ti ijọba apapọ, ijọba ipinlẹ tabi ijọba ibilẹ ki wọn to ṣe ayẹwo ti eto BSHSI FAP. A nireti pe awọn alaisan yoo fi ọwọ sowọ pọ pẹlu BSHSI ki wọn si fun BSHSI ni atotonu lasiko to yẹ lati gba owo iranwọ. A o ṣe iwuri fun ẹnikẹni to ba ni owo lati ra eto adojutofo gẹgẹ bi ona to daju lati gba awọn eto ilera ni ọna to fini lọkan balẹ to gbòòrò síi, to si wa fun gbogbo eto ilera.

Ni awọn igba miran, awọn ofin to wa fun ijọba ipinlẹ yoo fi kun ojuṣe tabi gbe ojuṣe miran fun awọn ile iwosan to ni ile iṣe ni awọn ipinle bẹẹ. Erongba eto yii ni lati tẹle ofin ijọba apapọ ati ofin ịjọba ipinlẹ in iru awọn ipinlẹ bẹẹ. Fun idi eyi, awọn agbekalẹ kan wa ni awọn ipinle kan nikan gẹgẹbi a ṣe fi si isalẹ yi.

Osuwọn Lati Kopa(Eligibility Criteria)

1. Fifi owo iranwọ funnni yoo da lori bi eni naa ṣe nilo owo si, ko si ni da lori ẹya , ẹsin, awọ, ọkọ tabi aya nini, akọ tabi abo, ọjọ ori, ipo igbeyawo, orirun, eto boya okunrin nifẹ lati maa ba obinrin lajọsepọ tabi boya ọkunrin nifẹ lati maa ba ọkunrin lajọsepọ (sexual orientation), didarapọ mọ akọ tabi abo, alaye nipa ajogunba, ipo awọn ajagun fẹyinti, alaabọ ara, tabi awọn eto miran ti ofin fọwọ si.

2. Iye Owo Ti Alaisan Jẹ (Amounts Charged to Patients)
   Eto FAP peṣe ida ọgọrun ninu ọgorụn (100%) iranwọ owo fun eto awọn to lẹtọ fun iranwo fun awọn ti ko ni eto adojutofo ati awọn to ni eto adojutofo, ti gbogbo owo osu ọdọọdun idile jẹ tabi to kere si ida igba ninu ọgọrun (200%) ninu awọn Ilana ijọba Apapọ nipa àìní (Federal Poverty Guidelines (FPG)) gẹgẹ bi wọn ṣe ma nṣe ayipada rẹ lọdọọdun. BSHSI tun gbe eto ẹdinwọ jade fun awọn alaisan ti gbogbo owo osu wọn ni ọdun kan jẹ laarin ọkanlerugba ninu ọgọrun (201%) si irinwo ninu ọgorun (400%) ninu eto EFG (AFIKUN D).

3. AGB
   Eni ti o ba yẹ fun eto FAP tabi ẹni ti ko ni eto adojutofo, ko nii san kọja owo to wa fun eto AGB fun itọju pajawiri tabi awọn itọju miran to nilo eto iwosan. BSHSI fun awọn ti ko ni eto adojutofo ti wọn ko si ni ẹtọ lati gba iranwọ owo ni ẹdinwo. ọwo ti wọn din fun awọn eniyan yi jẹ AGB. Eto AGB ma nyipada nipa ohun to nṣele ninu ọja, a si lee mọ nipa lilo 'ọna ẹyin wiwo ti o nlo idiyele Medicare ati idiyele ninu oko òwồ' (look back method utilizing Medicare and commercial rate ) , pẹlu awọn ọja ti wọn ni lati san owo wọn papọ (co payment) ati awọn owo ti wọn ni lati yọ kúrò. (deductible) (AFIKUN E).

4. Awọn To Ṣeéṣe Ki Wọn Lẹtọ (Presumptive eligibility)
   Awọn igba miran wa to jẹ pe o dabi ẹni pe alaisan ti ko ni eto adojutofo lẹtọ si eto iranwọ owo sugbọn ti alaisan naa ko tii pese awọn iwe ti yoo gbe e lẹsẹ pe o lẹtọ si eto naa. Ni iru apẹẹrẹ yii, a le gba iṣiro owo osu alaisan ati/tabi iye owo ijọba apapọ lori ipo àìní (Federal Poverty Level) lati awọn ọna miran bii: awon ile iṣe to nyani lowo, ti wọn maa fi ẹri to daju han lori idi ti alaisan náà fi nilo iranlọwọ owo. Eto awon to ṣeṣe ki wọn lẹtọ si owo iranwọ da lori ṣiṣe agbeyẹwo awọn to ba kan ni ọ̀kọọkan, o si wa fun iṣẹlẹ kan pato.

5. Asiko Ti Wọn Le Kopa
   Awon alaisan le bere fun owo iranwọ titi ọjo to to òjìlérúgba ọjọ́ (240 days) lẹyin idiyele akọkọ. Ti alaisan ba yege ninu ibeere rẹ lati gba owo iranwọ, o le lo owo iranwọ naa fun ọjọ to to òjìlérúgba ọjọ́ (240 days) siwaju igba ti o ṣe ibeere ati òjìlérúgba ọjọ́ (240 days) lẹyin igba ti o ti buwọ lu iwe ibeere iranlọwo. Awọn alaisan to ba yege fun eto iranwọ owo to tun pada wa si ile iwosan fun itọju laarin òjìlérúgba ọjọ́ (240 days) yoo kopa ninu eto adojutofo fun eto ilera ijọba apapọ, ijọba ipinlẹ ati ijọba ibilẹ ni gbogbo igba ti o ba wa fun itọju. Eto owo iranwọ ti BSHSI nṣe kii ṣe eto adojutofo.

   Gbogbo awọn ti kii ṣe ọmọ onilu ati awọn ti wọn ni iwe igbelu ni o lẹtọ si owo iranwọ. Sugbọn, a o ṣe ayẹwo awọn alaisan to ni iwe iwọlụ (visa) ni ẹyọ kọọkan lati mọ boya wọn lẹtọ lati kopa. Ti a ba gba alaisan kan laaye lati jẹ anfaani owo iranwọ, igbalaye yẹn wa fun itọju yẹn nikan, kiise fun òjìlérúgba ọjọ́ (240 days) ki o to tọwọ bọ iwe ibeere tabi òjìlérúgba ọjọ́ (240 days) ti o ti tọwọ bọ iwe ibeere. Awọn alaisan ni lati pese ẹda iwe iwọlu wọn ati awọn iwe adojutofo, iwe owo ati/tabi atotonu lori ẹni ti yoo san owo wọn.

6. Awọn Ile Isẹ To Nkopa (Participating Providers)
   Awọn oṣiṣẹ eleto ilera ti wọn kii ṣe oṣiṣẹ BSHSI kan maa nṣe awọn itọju awọn aisan kan ati awọn itọju pajawiri, wọn si le se idiyele iṣe itọju ti won ba ṣe lọtọ ti wọn ko si nii tẹlẹ eto owo iranwọ . Wo AFIKUN F fun alaye ni kikun nipa atojọ awọn eleto ilera ti wọn nse itọju pajawiri ati awọn itọju to yẹ, sugbọn ti wọn ko ti tẹle eto owo iranwọ ti BSHSI nṣe.

**ETO AWỌN ILANA**

Wo Afikun G fun eto awọn ilana.

Awọn Alaṣẹ Ajọ ile iṣe BSHSI lo fi ontẹ lu eto yi

Fun idiyele ati owo gbigba, jọwọ wo eto idiyele wa ati awọn eto owo gbigba wa.

## AFIKUN A

Eto Ẹdinwo AGB

Alaye siwaju sii nipa eto ẹdinwo wa lori ikanni ayelujara wa lori: www.fa.bonsecours.com tabi ki ẹ pe ẹka itọju onibara wa lori (Ni ilẹ yi) 804-342-1500 tabi (Laisan owo) 1-877-342-1500. Fun itọju onibara ti ile iwosan gbogbonişe ti Rappahannock, jọwọ pe 804-435-8529.

AFIKUN B

AWỌN ILANA IJỌBA APAPỌ NIPA ÀÌNÍ

Tabili to wa ni isalẹ yi da lori awọn ilana ijọba apapọ fun àìní fun ti ọdun 2016

| # Awọn eeyan to wa ni inu Ẹbi tabi Idile | Awọn ipinle meji dinlaadọta ti ilẹ Amẹrika ti wọn wa papọ pẹlu D.C. | Ida igba ninu ọgorun ninu FPL (200% FPL ) | Ida ọọdurun ninu ọgorun ninu FPL (300% FPL) | Ida irinwo ninu ọgorun ninu FPL (400% FPL) |
|---|---|---|---|---|
| Ookan | $11,880 | $23,760 | $35,640 | $47,520 |
| Eeji | $16,020 | $32,040 | $48,060 | $64,080 |
| Ẹẹta | $20,160 | $40,320 | $60,480 | $80,640 |
| Ẹẹrin | $24,300 | $48,600 | $72,900 | $97,200 |
| Aarun | $28,440 | $56,880 | $85,320 | $113,760 |
| Ẹefa | $32,580 | $65,160 | $97,740 | $130,320 |
| Eeje | $36,730 | $73,460 | $110,190 | $146,920 |
| Ẹẹjọ | $40,890 | $81,780 | $122,670 | $163,560 |
| Ẹnikọọkan ti o ba kun wọn | $4,140 | $8,280 | $12,420 | $16,560 |

# AFIKUN C

## GBIGBA ALAYE NIPA OWO IRANWỌ

Awọn alaisan le gba iwe ibeere fun owo iranwọ lati ori ikanni ayelujara wa: www.fa.bonsecours.com, lọwọ Akọwe agba tabi oludamọran nipa ọrọ owo ti o wa ni eyikeyi awọn ọgba ile iwosan wa, tabi ki ẹ pe ẹ̀ka itọju onibara wa lori (Lábẹ̀lé) 804-342-1500 tabi (Laisan owo) 1-877-342-1500. Fun ẹ̀ka itọju onibara ti ile iwosan gbogbonișe ti Rappahannock, jọwọ pe 804-435-8529. Fun awọn alaisan ti wọn ngbe ni ipinlẹ Maryland, ofin ipịnlẹ naa mu u ni dandan pe ẹ ni lati fi ọwọ si iwe ibeere fun iranwọ owo to yatọ, ẹ si le ri iwe ibeere naa lori ikanni ayelujara to wa ni oke yi, tabi ki ẹ pe awọn nọmba ẹrọ ibanișorọ to wa loke yii.

AFIKUN D

IYE OWO TI WỌN NI AWỌN ALAISAN SAN (AMOUNTS CHARGED TO PATIENTS)

| Ọja in Ilu | Eto ẹdinwo to kere si tabi to jẹ nkan kan-naa pẹlu ida igba ninu ida ọgọrun ninu eto FPL (<=200% FPL) | Eto ẹdinwo wa to lati ida ọkanlerugba ninu ida ọgorun si ida ọọdunrun ninu ọgọrun ninu eto FPL (Discount 201-300% FPL) | Eto ẹdinwo to wa lati ida ọọdunrun ninu ida ọgorun si ida irinwo ninu ida ọgọrun ninu eto FPḶ (Discount 301-400% FPL) |
|---|---|---|---|
| Ilu Baltimore | Ida ọgorun ninu ọgọrun (100%̩) | Ida mejilelaadọrin ninu ọgorun (72%) | Ida eejidinlaadọrin ninu ọgọrun (68%) |
| Ilu Hampton | Ida ọgorun ninu ọgọrun (100%̩) | Ida ẹẹtalelọgọrin ninu ọgọrun (83%) | Ida ọọkandinlọgọrin ninu ọgọrun (79%) |
| Ilu Kentucky | Ida ọgorun ninu ọgọrun (100%̩) | Ida ẹẹtalelọgọrin ninu ọgọrun (83%) | Ida ọọkandinlọgọrin ninu ọgọrun (79%) |
| Ilu Rappahannock | Ida ọgorun ninu ọgọrun (100%̩) | Ida mejilelaadọrin ninu ọgorun (72%) | Ida eejidinladọrin ninu ọgọ (68%) |
| Ilu Richmond | Ida ọgorun ninu ọgọrun (100%̩) | Ida ẹẹtalelọgọrin ninu ọgọrun (83%) | Ida ọọkandinlọgọrin ninu ọgọrun (79%) |
| Ilu South Carolina | Ida ọgorun ninu ọgọrun (100%̩) | Ida eejidinladọrun ninu ọgọrun 88% | Ida ẹẹrinlelọgọrin ninu ọgọrun (84%) |

APPENDIX E

AWỌN IDIYELE TI BSHSI MA NSABA GBE LORI ỌJA RẸ

| Ọja BSHSI | AGB |
|---|---|
| Ilu Baltimore | Wo isalẹ* |
| Ilu Hampton | Ida mẹẹdọgbọn ninu ọgọrun (25%) |
| Ilu Kentucky | Ida mẹẹdọgbọn ninu ọgọrun (25%) |
| Ilu Rappahannock | Ida marundinlogoji ninu ọgọrun (35%) |
| Ilu Richmond | Ida mẹẹdọgbọn ninu ọgọrun (25%) |
| Ilu South Carolina | Ida ogun ninu ọgọrun (20%) |

**Ilu Baltimore**

**Ile Iwosan Bon Secours**
2000, West Baltimore Street | Baltimore, MD 21223

*Nitori pe ofin Ipinlẹ Maryland ati ofin Ijọba apapọ lori owo ori fi gbedeke si owo ti a le ni ki alaisan san, ẹni to ba lẹtọ si eto FAP tabi ẹni ti ko ni eto adojutofo, ko nii gba idiyele to pọ ju eyi to kere julọ ninu AGB tabi gbedeke iye owo ti awọn ajọ to nṣe ayẹwo owo itọju ni ipinlẹ Maryland (Maryland Health Services Cost Review Commission) fi lelẹ fun itọju pajawiri tabi fun awọn itọju miran to nilo iwoṣan .

**Ilu Hampton**

**Ile Iwosan Bon Secours ni Maryview**
3636, High Street| Portsmouth, VA 23707

**Ile Iwosan Mary Immaculate**
2, Bernardine Drive | Newport News, VA 23602

**Ile Iwosan Bon Secours DePaul**
150, Kingsley Lane | Norfolk, VA 23505

**Ilu Kentucky**

**Ile Iwosan Our Lady of Bellefonte**
St. Christopher Drive | Ashland, KY 41101

**Ilu Rappahannock**

**Ile Iwosan Gbogbogbo Bon Secours Rappahannock**
101, Harris Road | Kilmarnock, VA 22482

**Ilu Richmond**

**Ile Iwosan ST. Mary**
5801, Bremo Road| Richmond, VA 23226

**Ile Iwosan Memorial Regional**
8260, Atlee Road| Mechanicsville, VA 23116

**Ile Iwosan Richmond Community**
1500 N. 28th Street | Richmond, VA 23223

**Ile Iwosan ST. Francis**
13710 Francis Boulevard |Midlothian, VA 23114

**Ilu South Carolina**

**(ST. Francis Downtown)**
1, St. Francis Drive | Greenville, SC 29601

**ST. Francis Eastside**
125, Commonwealth Drive | Greenville, SC 29615

**ST. Francis Millennium**
2, Innovation Drive| Greenville, SC 29607

AFIKUN F

Awọn Onișegun to Nkopa Ninu Eto Itoju

Fun atojọ awọn onișegun to nșe itọju pajawiri tabi awọn itọju miran to yẹ ti wọn ko si tii maa tẹle ilana owo iranwọ BSHSA, jọwo lọ si ori ikanni ayelujara: www.fa.bonsecours.com.

ATOJỌ G

AWON ILANA ETO

A ṣe awon ilana yi lati le ran awọn oṣiṣe lọwọ ki wọn ba le mu awọn ala eto yii ṣẹ. Nigba ti wọn ba ntẹle awọn ilana eto yii, awọn oṣiṣe ni lati lo ọgbọn ori wọn nibi ti iṣe wọn mọ ati/tabi ibi ti ojuṣe wọn mọ.

Ilana ṣiṣe Amuyẹ (Eligibility Process)
A o lo awon ilana wọnyi lati mọ boya alaisan lẹtọ si eto owo iranwọ:

(A) Alaisan tabi aṣoju alaisan yoo fi ọwọ si iwe ibeere. Iwe ibeere wulo fun gbigba atotonu to ṣe dandan nipa alaisan lati le mọ boya alaisan lẹtọ si owo iranwọ.

(B) A le lo awọn atotonu miran lati ita lati gba atotonu lati mọ boya alaisan tabi oniduro alaisan le san owo itọjụ (fun apẹẹrẹ siṣe gbedeke iye gbese ti eniyan le jẹ, iyen special credit scoring)

(C) Awọn alaisan ni lati ni owo ti o to ninu akanti wọn ki wọn si ti dajọ itọju sọna pẹlu BSHSI, ki wọn to beere fun owo iranwọ, a le ṣo boya alaisan yẹ eto naa ninu akoko owo gbigba.

(D) Awọn alaisan to ba kọ lati kopa ninu eto awọn ile iṣe to nṣiṣe pẹlu wa lati mọ boya alaisan lẹtọ si eto iranwọ owo tabi awọn alaisan to ba kọ lati fi ọwọ so ọwọ pọ pẹlu awọn ile iṣe to nṣiṣe pẹlu wa lati mọ boya alaisan lẹtọ si eto iranwọ owo labẹ eto yii, ko nii le kopa ninu eto yii. A o ṣe agbẹyẹwo ẹdinwo ti a ba fun alaisan lọtọọtọ ti ko ba wa ni ibamu pẹlu eto yii, a si le gba a wọle tabi ki a ma gba a wọle bí ààyè ẹnìkọ̀ọ̀kan bá ti rí.

(E) A o kàn si olubeere fun owo iranwọ nipa lilo lẹta ori ayelujura (imeeli)ti a ba nilo awon atotonu miran. Leta naa yoo sọ fun olubeere pe ki o fi atotonu naa sọwọ si wa laarin ọgbọn ọjọ ti o ba gba lẹta naa. Ti a ko ba gba atotonu naa laarin ọgbọn ọjọ iṣẹ, a ko nii gbe igbesẹ kankan mọ lori ibeere olubeere fun owo iranwọ náà.

(F) BSHSI yoo gbe igbesẹ lori Ibeere fun iranwọ owo ni kiakia, BSHSI yoo si rii pe o sa gbogbo agbara rẹ lati rii pe a kan si alaisan fun iroyin lori boya ibeere rẹ yọri si rere tabi ko yọri si rere laarin ọgọta ọjọ (60 days)ti a ti gba iwe ibeere ti olubeere kọ.

(G) Fun Ile Iwosan Maryland nikan : Ẹ le gbe Igbesẹ ko-tẹmi-lọrun lori ibeere yin fun owo iranwọ nipa pipe ẹka itọju onibara wa lori nọmba ẹro ibanisọrọ (Laisan owo) 877-342-1500. .

Siṣe Iwadi Owo To Nwọle
A o lo awọn iwe wonyi lati ṣe iwadi owo ti o nwọle fun idile rẹ.

(A) Iwe owo ori ti o ti san fun idile alaisan ni ọdun to ṣẹṣẹ kọja lọ.
- Ti alaisan náà ba jẹ ọ̀ṣìṣẹ́ aladani, ẹda iwe to nṣe afihan owo to wọle fun ile iṣẹ rẹ pẹlu iwe owo ori fun ile iṣe rẹ ati fun ara rẹ fun ọdun to ko ja ti o san ti o si ti dapada.

(B) Iwe ti o nṣe afihan owo osu rẹ fun osu mẹta ti o ṣẹṣẹ kọja lọ tabi iwe lati ọdọ awọn agbaniṣisẹ rẹ.

(C) Lẹta Awọn ajẹmọnu nibi iṣẹ ti o ngba lọwọlọwọ to ṣe afihan boya ibeere rẹ yọri si rere tabi o fori sanpọn ati iye owo ti o gba.

(D) Lẹta iranlọwọ ìjọba (Social Security) ti o ṣẹṣẹ jade tabi iwe akanti ile

ifowopamọ to nfi owo to nwọle si nipaṣẹ iranlọwo ìjọba.

(E) Iwe akanti ifẹyinti.

(F) Lẹta SNAP.

(G) Iwe ti ile ẹjọ pa lasẹ tabi awọn lẹta obi ti ko fi ọmọ sọdọ ti o nsọ iye owo iranwọ fun ọmọ ti wọn ti gba.

(H) Iwe adehun fun ohun elo yiya tabi iwe to nṣe afihan gbogbo owo to nwọle nipa yiya ohun elo sita (rental income).

(I) Iwe to nṣe atopọ awọn ohun to ni iye lori bii, ipin idokowo, Ipin idokowo to jẹ gbese fun ile iṣẹ (Bonds), awọn CD, tabi awọn dukia miran ti alaisan náà le ni.

(J) Ẹda to kun rẹrẹ fun eyikeyi akanti to nlo iwe sọwedowo, akanti ifowopamọ, tabi awọn akanti ọja owo.

Biotilẹjẹpe, a beere fun ẹri owo to nwọle fun ayẹwo fun eto owo iranwọ alaisan (Patient Financial Assistance Program), awọn ofin eto ibilẹ DSH le nilo ẹri owo to nwọle. A ṣe agbeyẹwo awọn ofin bẹẹ lẹyọ kọọkan lati rii pe a tẹle awọn eto ibilẹ DSH (Local System DSH programs)

<u>Ayẹwo Awọn To Ṣeeṣe Ki Wọn Lẹtọ (Presumptive Eligibility Verification)</u>

Gẹgẹ bi atotonu ti alaisan fi silẹ tabi eyi ti BSHSI fi silẹ, alaisan le ni anfaani lati gba iranwọ owo ida ọgọrun ninu ọgọrun (100%), laini lati kọ iwe ibeere fun iranwọ owo, labẹ awọn idi wọnyi:

(A) Alainilelori

(B) Awọn alaisan ti wọn ran si wa lati ọdọ ẹgbẹ awọn ile iwosan ti kii gba owo lọwọ alaisan (National Association of Free Clinics).

(C) Kikopa ninu awọn eto awọn obirin, awọn ọmọ ọwọ ati awọn ọmọde (WIC).

(D) Eto iranwọ lati ra ounjẹ ni ẹdinwo (SNAP).

(E) Lẹto si awọn eto awọn ipinlẹ tabi ijọba ibilẹ ti wọn ko ni owo lati ṣe ojuṣe wọn (Fun apẹẹrẹ Awọn ti owo osu wọn kọja gbagede lati jẹ anfani eto Medicaid ti wọn si fẹ lẹtọ si eto medicaid (Medicaid Spend Down).

(F) Alaisan to ti ku pẹlu ida igba ninu ọgorunị (200%) ninu eto FPL pẹlu dukia ile tabi ilẹ ti a ko mọ.

(G) Alaisan ni akanti owo ko to di pe won lu ofin wiwọ gbese bi o ti wa ninu Abala keje (Chapter 7) ati FPL wọn si kere si ida igba ninu ọgọrun

(H) Awọn idena miran to ṣe koko wa ti ko jẹ ki alaisan ri owo san.

<u>Ifitónilétí Eto Owo Iranwo</u>

BSHSI yoo gbiyanju lati rii pe a ṣe alaye nipa awọn eto wa ki a si ṣe ipolongo wọn ni ọna to han ketekete fun gbogbo awọn eniyan. Enikẹni le gba ẹda iwe ibeere fun eto owo iranwọ lori ikanni ayelujara: www.fa.bonsecours.com. BSHSI yoo tun pese ikanni ayelujara fun ẹnikẹni to ba beere . Ẹnikẹni le gba iranwọ lati kọ iwe ibeere eto iranwọ lati eyikeyi ibudo iforukọsilẹ wa, lọdọ awọn oludamọran nipa ọrọ owo tabi awọn ile iṣe olukawo. Iyara ile iṣẹ awọn oludamọran nipa ọrọ owo ati iyara ile iṣe olukawo ni awọn ibudo iforukọ sile awọn alaisan. Enikẹni le ya ọdọ eyikeyi ninu awọn ijoko fun alaye wa to wa ninu ọkọọkan awọn ile iwosan wa lati beere fun iranlọwọ lati ri awon oludamọran nipa ọrọ owo tabi iyara ile iṣẹ olukawo. Ẹnikẹni si le gba ẹda iwe ibeere owo iranwọ ati eto nipasẹ lẹta lori ayelujara (imeeli) lọfẹ, nigba ti wọn ba pe ẹka itọju onibara wa lori (Lábẹ́lé) 804-342-1500 tabi (Laisan owo) 1-877-342-1500. Fun èka itọju onibara ti ile iwosan gbogboniṣe ti Rappahannock, jọwọ pe 804-435-8529.

<u>Eto Idiyele ati Eto Owo Gbigba.</u>

Fun awọn ilana idiyele ati owo gbigba wa jọwọ wo eto idiyẹle ati eto gbigba owo. Eto yii ṣe ilasilẹ awọn igbeṣe ti BSHSI le gbe ti ẹ ko ba san owo. Ẹnikẹni le gba ẹda iwe awọn eto idiyele ati gbigba

owo lori ikanni ayelujara: www.fa.bonsecours.com. Ẹnikẹni tun le gba iwe eto yii ni eyikeyi awọn agbegbe iforukọsilẹ wa, lọdọ awon oludamọran nipa ọrọ owo tabi iyara ile iṣẹ olukawo. Iyara ile iṣe oludamọran nipa ọrọ owo ati ti olukawo ninu agbegbe iforukọsilẹ awọn alaisan. Ẹnikẹni lee ya eyikeyi awọn ijoko eto alaye ti o wa ninu ile iwosan kọọkan lati gba iranwọ lati ri awon oludamọran nipa ọrọ owo tabi iyara ile iṣẹ olukawo. Ẹnikẹni si le gba ẹda iwe eto idiyele ati eto gbagba owo lori ayelujara (imeeli) lọfẹ, nigba ti wọn ba pe ẹka itọju onibara wa lori (Lábẹ́lé) 804-342-1500 tabi (Laisan owo) 1-877-342-1500. Fun eto itọju onibara ti ile iwosan gbogboniṣe ti Rappahannock, jọwọ pe 804-435-8529

<u>Fun Ile Iwosan Maryland Nikan</u>: Ni afikun pẹlu awọn ilana to wa loke yii ati awọn ojuṣe, awon ilana miran kan wa fun awọn alaisan to nwa itọju ni ile iwosan BSHSI to wa ni Maryland.

- A o lo "iwe atotonu fun ile iwosan" lati jẹ ki awọn awọn obi mọ nipa awọn atotonu to wa loke yii ati awọn wọnyi (1)Itọsọna lori ọna ati kọ iwe ibeere fun eto iranwọ fun ilera ti Maryland ( Maryland Medical Assistance Program) ati awọn eto miran to le ran ẹ lọwọ lati san owo ti o jẹ. (2) Atotonu lati kan si eto iranwọ fun ilera ti Maryland (Maryland Medical Assistance Program); ati (3) Gbolohun ti a kọ, nibi to ti wulo, pe owo iṣe onişegun ko si ninu idiyele ti ile iwosan wa nṣe ati pe idiyele mejeji wa lọtọọtọ. A o fun alaisan ni iwe atotonu ile iwosan yii (a) ki alaisan to kuro ni ile iwosan; (b) pẹlu idiyele ile iwosan; ati (c) ti wọn ba beere.